# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## LÉKÈ Ọ̀PỌ̀ ÈNÌYÀN BÍ?

## Ìtàn ...

**Matteu 26:31-75**

Peteru fẹ́ràn Jesu, ṣùgbọ́n o ma nfẹ́ ki ọ̀pọ̀ ènìyàn ṣe ẹlẹri fún oun. Nibi ounjẹ alẹ́ ikẹhin nígbàtí Jesu nkìlọ̀ fun awọn aposteli pe gbogbo wọn ni yio sẹ oun, Peteru dide duro pẹlu ìgberaga, o si jẹ́ ẹ̀jẹ́ pe bi gbogbo eniyan tilẹ̀ kọsẹ̀ lara Jesu, oun ki yio kọsẹ̀ lai. Jesu dahun pe, "Li oru yi, ki akukọ ki o to kọ, iwọ o sẹ mi nigbà mẹta." Ẹṣẹ ikẹrinlelọgbọn (34).

Peteru ni èrò rere, ṣùgbọ́n kò mọ̀ pé ìgbéraga wà lọkan rẹ̀. Nigbàti ó di àṣálẹ́, awọn ọ̀pọ̀ ènìyàn wá lati mu Jesu, gbogbo awọn ọmọ ẹ̀hin sì nwòran, Peteru si fa idà yọ, láti gba ọ̀gá rẹ̀ silẹ̀. Lẹhin ìwọ̀n bi wakati melokan si i ni awọn ọ̀tá Jesu wa nfi Peteru ṣe yẹ̀yẹ́, o sì sẹ́ Jesu lẹ̀ẹmẹta pe oun kò mọ Jesu. Bẹ̀ẹ̀ni Peteru nní ìgboyà si i, titi ti o fi nbúra tó sì nsépè (Ẹsẹ 74).



Bẹ̀ẹ̀ni akukọ kọ. Ni akókò naa Jesu wà ni gbàngàn idajọ́, ti awọn olusọ ti nnà án. Peteru si ri Jesu bo ṣe wò ó pẹlu ìfẹ́ ati aanu, o si bọkanjẹ́. "Peteru si rantí ọ̀rọ̀ ti Jesu wi fun un, Ki akukọ ki o to kọ, iwọ o sẹ́ mi lẹrinmẹta. Peteru si bọ si ode, o sọkún kíkorò." Luku 22:61,62.

Lati ọjọ́ naa lọ, ni Peteru ti di ọkunrin ọ̀tọ̀, kò gbe igbé ayé rẹ̀ lati wu ọ̀pọ̀ ènìyàn mọ́, ṣùgbọ́n o pinnu lati má a wu Ọlọrun nìkan soso. Lẹhin ti Peteru ti yípadà tán, tí a sì mu u wá si iwájú ajọ ìgbìmọ̀ awọn Ju, wọn nà án, wọn sì kìlọ̀ fun pé ki ó máṣe kọni nipa Jesu mọ́, Peteru dahun laifòyà pé, "Awa kò gbọdọ̀ ma gbọ́ ti Ọlọrun ju ti ènìyàn lọ." Iṣe Awọn Aposteli 5:29. Peteru tẹsiwajú lati jẹ olotitọ ati ẹni to fẹ́ràn Jesu nigbàtí o yàn ki a kàn oun mọ agbelebú ni idori-kodò nipaṣẹ awọn alaṣẹ ijọba Romu ju ki o tún sẹ Jesu lọ.

AMAZING FACTS

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

1. Bawo ni Ọlọrun ṣe ma nmọ̀ bi a bá jẹ́ ti Rẹ̀ tàbí a kí iṣe ti Rẹ̀?
   **Matteu 7:21**
   Ki iṣe gbogbo ẹniti npè mi li Oluwa, Oluwa, ni yio _________ ijọba ọrun; bikoṣe ẹniti _________ ifẹ ti Baba mi ti mbẹ li ọrun.
   **Romu 6:16**
   Ẹnyin kò mọ̀ pe, ẹniti ẹnyin ba _________ ara nyin lọ́wọ́ fun bi ẹrú lati maa gbọ́ tirẹ, ẹrú ẹniti ẹnyin ba _________ tirẹ̀ li ẹnyin iṣe; ibaaṣe ti ẹ̀ṣẹ̀ sinu ikú, tabi ti igbọran si ododo?
   Àkíyèsí: Ìlànà ti o rọrùn ni pe a le e mọ ẹni ti a jẹ́ olotítọ́ sí nígbàti a bá ngbọ́ tirẹ̀. Bi a ba sọ pé ìránsẹ Ọlọrun ni wa ṣùgbọ́n ti o jẹ wipé ọ̀dọ̀ eṣu tàbí ọ̀dọ̀ ayé ni a ti ngba ìmọ̀ràn, se ni a ntan ara wa jẹ.

2. Nígbàtí òfin Ọlọrun ati òfin eniyàn ba ta ko ara wọn, ti tani Peteru sọ pe ki a gbọ́?
   **Iṣe Awọn Aposteli 5:29**
   Ṣùgbọ́n Peteru ati awọn aposteli dahùn, nwọn si wipé, Awa kò gbọdọ̀ má gbọ́ ti _________ ju ti eniyàn lọ.
   Àkíyèsí: Lẹhin iyípadà Peteru ti o si tún ti fẹ́ràn Jesu, o sọ fun awọn Ju pé ẹniti oun kọ́kọ́ sowọ́pọ̀ pẹlu ni Ọlọrun. A ti kọ́ wa pe ni ìkẹhìn ọjọ́, ofin ẹranko naa àti ti ayé yio tako òfin Ọlọrun. A gbọ́dọ̀ yàn níbayi lati gbọ́ràn si òfin Ọlọrun - a kò gbọdọ̀ ronu ohun ti yio ṣẹlẹ lẹhin rẹ̀.

3. Bawo ni a ṣe le e fi ìfẹ́ wa si Ọlọrun hàn?
   **Johannu 8:31**
   Nitori naa Jesu wi fun awọn Ju ti o gbà á gbọ́ pe, Bi ẹnyin ba duró ninu _________ mi, nigbà naa li ẹnyin jẹ ọmọ-ẹhin mi nitootọ.
   **Johannu 14:15**
   Bi ẹnyin ba fẹ́ràn mi, ẹ ó ________ òfin mi mọ́.
   **1 Johannu 2:4**
   Ẹniti o ba wipe, emi mọ̀ ọn, ti kò si pa _______ rẹ̀ mọ́, èké ni, otitọ kò si si ninu rẹ̀.
   Àkíyèsí: Ọ̀nà tó dára julọ lati fi ìfẹ́ wa si Jesu hàn ni lati ṣe ìfẹ́ Rẹ̀, ìfẹ́ Ọlọrun pípé ni a sì fi hàn ninu òfin Rẹ̀ (Orin Dafidi èò:ì).

4. Gẹ́gẹ́ bi ọ̀rọ̀ Jesu, kiló de ti awọn àgàbàgebè ma ndabi ẹlẹsin?
   **Matteu 6:2**
   Nitori naa nigbàti iwọ ba nṣe itọrẹ aanu rẹ, máṣe fun fèrè niwajú rẹ, bi awọn agabagebe ti nṣe ni sinagogu ati ni ita, ki nwọn ki o le gbà _______ eniyan. Lootọ ni mo wi fun nyin, Nwọn ti gbà èrè wọn na.
   **Matteu 6:5**
   Nigbàtí iwọ ba ngbadura, máṣe dabi awọn agabagebe: nitori nwọn fẹ ati maa duro gbadura ni sinagogu ati ni igun ọ̀nà ìta, ki eniyan ki o ba le ________ wọn. Lootọ ni mo wi fun nyin, Nwọn ti gbà èrè wọn na.
   Àkíyèsí: Bibeli sọ fun wa pé, "ènìyàn a ma wo ojú, OLUWA a ma wo ọkàn." 1 Sameuli 16:7. Ojulówó Kristiani yio ma ronú lori ohun ti Ọlọrun nrò nípa rẹ̀ ki iṣe ohun ti ayé nrò nípa rẹ.

5. Njẹ̀ ààbò tó dajú wà nínú titẹ̀lẹ́ ọ̀pọ̀ ènìyàn bí?
   **Eksodu 23:2**
   Ìwọ kò gbọdọ̀ _________ ọ̀pọ̀lọpọ̀ eniyan lẹhin lati ṣe ibi, bẹ̃ẹni iwọ kò gbọdọ sọ̀rọ̀ li ọ̀ràn ki o tẹ̀ si ọ̀pọ̀ eniyàn lati yi ẹjọ́ po.
   **Matteu 7:13,14**
   Ẹ ba ẹnu-ọ̀nà híhá wọle; gbòrò li ẹnu-ọ̀na naa, ati onibu li ojú-ọ̀nà naa, ti o lọ si ibi _________, _________ li awọn ẹniti mba ibẹ̀ wọle, Nitori pe híhá ni ẹnu-ọ̀nà naa, ati toro li ojú-ọ̀nà naa, ti o lọ si ibi ìyè, díẹ̀ li awọn ẹniti o nri i.
   **1 Peteru 3:20**
   Awọn ti o ṣe alaigbọran nigbà kan, nigbati suuru Ọlọrun duro pẹ ni saa kan ni ọjọ́ Noa, nigbàti nwọn fi nkàn ọkọ̀ ninu eyiti a gba ọkàn _________ _________ nipa omi, eyini ni ẹni mẹjọ.
   Àkíyèsí: Ìtàn sọ fun wa pe, ọ̀pọ̀ èrò ma nsabà ṣe aṣise ninu ìgbésẹ̀ wọn. Ọ̀pọ̀ ènìyàn naa ló fẹ́ sọ okuta pa Mose kí wọn sì padà si oko ẹrú ni Egypti (Numeri 14:4-10). Ọ̀pọ̀ eniyàn náà ló pariwo sókè wípé, "Kàn án mọ agbelebu, kàn án mọ agbelebu." Luku 23:21. Ọ̀pọ̀ eniyàn náà ni yio sì tún jẹ́ - ki iṣe ènìyàn díẹ̀ - ni yio gba àmì ẹranko náà ní ìkẹhìn ọjọ́ (Ifihan 13:16).

6. Bawo loṣe ma nri lára Jesu nigbàtí a ba fi òfin àtọwọ́dọ́wọ́ ènìyàn síwájú òfin Ọlọrun?
   **Marku 7:7,9**
   Ṣùgbọ́n _________ ni nwọn ntẹriba fun mi, ti nwọn nfi òfin eniyàn kọni fun ẹ̀kọ́, O si wi fun wọn pé, Lootọ li ẹnyin kọ̀ òfin Ọlọrun silẹ̀, ki ẹnyin ki o le pa òfin àtowọ́dọ́wọ́ ti _________ mọ́.

7. Ṣe a o mọ awọn Kristiani otitọ laarin ọ̀pọ̀ ènìyàn ni ìkẹhìn ọjọ́ bí?
   **Matteu 24:9**
   Nigbà naa ni nwọn o fi nyin funni lati jẹ ni ìyà, nwọn o si pa nyin: a o si _________ nyin lọ́dọ̀ _________ orilẹ-èdè nitori orukọ mi.
   **2 Timothy 3:12**
   Nitootọ gbogbo awọn ti o fẹ maa gbé igbé ____________ ninu Kristi Jesu, yio farada _________.
   **Ifihan 12:17**
   Dragoni naa si binu gidigidi si obinrin naa, o si lọ ba awọn iru-ọmọ rẹ̀ _________ _________, ti nwọn npa òfin Ọlọrun mọ́, ti nwọn si di ẹ̀rí Jesu Kristi mu.
   **Ifihan 13:15**
   A sì fi fun un lati fi ẹmí fun àwòrán ẹranko naa ki o maa sọ̀rọ̀, ki o si mu ki a _______Ọ̀gbogbo awọn ti kò foribalẹ̀ fun àwòrán ẹranko naa.
   Àkíyèsí: Ní ìkẹhìn ọjọ́, Satani ati awọn ọmọ-lẹhin rẹ̀ yio dìde ogun nlá si awọn ọmọ Ọlọrun tóótọ́ ti wọn gbà Bibeli gbọ́.

8. Njẹ́ ó ṣe é ṣe lati sìn Ọlọrun ati ọ̀pọ̀ ènìyàn papọ̀ bí?
   **Matteu 6:24**
   Kò sí ẹniti o le sìn oluwa mejì: nitori yálà yio _________ ọ̀kan, yio si _________ ekejì; tabi yio faramọ́ ọ̀kan, yio si yàn ekeji ní ìpọ́sí. Ẹnyin kò le sin Oluwa pẹlu mammoni.
   **Matteu 12:30**
   Ẹnití kò ba wà pẹlu mi, o nṣe ________ sí mi; ẹniti kò ba si bá mi kópọ̀, o nfọ́nká.
   Àkíyèsí: Ninu ìjà laarin Kristi ati Satani, kò sí ìlú tàbí ìletò kan tí kò ní kàn, kò se e ṣe ki ẹnikan kan jẹ́ olùwòran. Bi a kò bá ti sowọ́pọ̀ pẹlu Jesu, èyí tumọ̀ si pe, a nran eṣù lọ́wọ́ nìyẹn.




YOR-SP24.indd 1
12/21/12 12:48 PM

9. Njẹ́ àábò wà ninu pé ki a fẹ́ràn ọ̀rẹ́ tabi ẹbí wa ju Jesu lọ?
**Matteu 10:37**
Ẹnití ó bá fẹ́ baba tabi ________ jù mi lọ, kò yẹ ni temi: ẹniti o ba si fẹ ọmọkunrin tabí ọmọbinrin _______ mi lọ, kò sì yẹ ni temi.
**Luku 14:26**
Bí ẹnikan ba tọ̀ mi wá, tí kò si korira (kí o fẹran wọn díẹ̀) baba rẹ̀, ati iya, ati _______, ati ọmọ, ati arakunrin, ati arabinrin, àní ati ________ ara rẹ̀ pẹlu, kò le ṣe ọmọ-ẹ̀hìn mi.
**Matteu 12:50**
Nitori ẹnikẹni tí o ba nṣe ________ Baba mi ti mbẹ li ọrun, oun naa li arakunrin mi, ati arabinrin mi ati ________ mi.
Àkíyèsí: Jesu ntọ́ka si nínbí yi pé, ọ̀nà tó dára jù ti a le gbà lati dáàbò bo ìfẹ́ wa sí ẹniti a fẹ́ràn ni pé ki a fi Ọlọrun ṣe àkọ́kọ́ ninu ayé wa. Àṣìṣe tó burú jù ni pe ki a fi ìfẹ́ sí awọn ẹbí tabi ọ̀rẹ́ wa siwaju ìfẹ́ wa ati ojúṣe wa sí Olugbàlà ati Ẹlẹda wa kẹ́hìn.

10. Njẹ́ ọgbọ́n wà nínú fífi ohun ti a jẹ́ tabi ki a fi ọrọ̀ ayé sáájú Jesu bí?
**Matteu 16:26**
Nitori pé èrè kini fun eniyan, bi o jèrè gbogbo ________, ti o si sọ ẹ̀mí rẹ̀ nù? tabi kili eniyan ìbá fi ṣe paṣiparọ_________ rẹ̀?
**Luke 12:15**
O si wi fun wọn pé, Kiyesara ki ẹ si maa ṣọra nítorí ojúkòkòrò: nitori igbesí ayé eniyan ki iduro nípa ọ̀pọ̀ _________ tí ó ní.
Àkíyèsí: Ìgbàgbọ́ ninu pé, ayọ̀ ati àábò ati awọn ohun rere ma nwá lati inu iṣẹ jẹ́ ìgbàgbọ́ ti yio yọrí si ìparun. Ní ìdàkejì, Jesu wípé, "O rọrùn fun ibakasiẹ lati wọ ojú abẹ́rẹ́, jù fun ọlọ́rọ̀ lati wọ ijọba Ọlọrun lọ." Marku 10:25.

11. Ṣé àábò wà ninu títẹ̀síwájú ní síṣe àìgbọràn si ìfẹ́ Ọlọrun lẹhin ti Ọlọrun bá ti fi òtítọ́ hàn wá tán?
**Hosea 4:6**
A _______ awọn eniyan mi kúrò nitori aini ìmọ̀: nitori iwọ ti _______ ìmọ̀ sílẹ̀, emi o si kọ̀ ọ́, ti ìwọ kì yio ṣe alufa mi mọ: níwọ̀n bi ìwọ ti gbàgbé òfin Ọlọrun rẹ, emi pẹlu o gbàgbé awọn ọmọ rẹ.
**Heberu 10:26**
Nitori bi àwa ba mọnmọ̀ dẹ́ṣẹ̀ ________ ìgbàtí àwa ba ti gbà ìmọ̀ ________ kò tún sí ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ̀ mọ́.

12. Kini yio sẹlẹ̀ si awọn ti wọn ntẹ̀síwájú lati ma a kọ òtítọ́?
**2 Tesalonika 2:10-12**
Ati pẹlu ìtànjẹ aiṣododo gbogbo fun awọn ti _________; nitori ti nwọn kò gbà ________ ________ ti a ba fi gbà wọn là, Ati nitori èyí, Ọlọrun ran ohun ti nṣiṣẹ́ ìṣìnà si wọn kí nwọn ki o le _________ ẹ̀ké gbọ́: Kí a le ṣe ìdàjọ́ gbogbo awọn ti kò gba otitọ́ gbọ́, ṣùgbọ́n ti nwọn ni inú dídùn ninu aiṣododo.
**Johannu 3:19**
Èyí ni ìdàjọ́ naa pé, ìmọ́lẹ̀ wá sí ayé, awọn eniyan si ________ òkùnkùn jù ìmílẹ̀ lọ, nitori ti iṣẹ́ wọn _________.
Àkíyèsí: Ìwé Mímọ́ kọ wa pé Jesu ni òtítọ́ (Johannu 14:6). Kíkọ̀ tabi gbígbà òtítọ́ ni ọ̀nàkọnà ni kíkọ̀ tàbí gbígbà Jesu.



13. Njẹ awọn ti yio ma a ṣe inúnibíni si awọn eniyàn Ọlọrun ni ìgbà ìkẹhìn yio gbàgbọ́ pé awọn nṣe ohun rere bí?
**Johannu 16:2**
Nwọn o yọ nyin kúrò ninu sinagogu: aní, àkókò mbọ̀, ti ẹnikẹni tí ó ba pa nyin, yio _________ pé oun nṣe _________ fun Ọlọrun.

14. Bawo ni Peteru ṣe ṣàpèjuwe awọn tó ti mọ òtítọ́ ti wọn sì kọ̀ lati tẹ̀lé e?
**2 Peteru 2:21,22**
Nítorí ìbá sàn fun wọn, ki nwọn ki o ________ mọ̀ ọ̀nà òdodo, jù lẹhin ti nwọn mọ̀ ọn tán, kí nwọn ki o _________ _________ ninu òfin mímọ́ ti a fi fun wọn, Òwe otitọ nì ṣẹ sí wọn lára, Ajá tún padà si èébì ara rẹ̀; ati ẹlẹdẹ ti a ti wẹ mọ́ sinu _________ ninu ẹrẹ̀.

15. Njẹ́ títẹ̀lé Jesu nílò ìjàkadì tabi ìsẹ́ra-ẹni bí?
**Luku 9:23**
O sì wí fun gbogbo wọn pé, Bi ẹnikan ba nfẹ lati maa tọ̀ mi lẹhìn, kí ó _______ ara rẹ̀, kí ó si gbé agbelebu rẹ̀ ni ijọ gbogbo, ki o si maa tọ̀ mi lẹhìn.

16. Njẹ́ àábò wà nínú sísún ìgbésẹ̀ lati tẹ̀lé Jesu síwájú bí?
**Heberu 4:7**
Ẹ̀wẹ̀, o yan ọjọ́ kan, o wi ninu Iwe Dafidi pé, Loni, lẹhin ìgbà pipẹ́ bẹ́ẹ̀; bi a ti wí nìṣaaju, Loni bi ẹnyin ba ________ ohùn rẹ̀, ẹ máṣe sé ọkàn nyin le.
**Heberu 2:3**
Awa o ti ṣe là a, bi awa kò ba ________ irú ìgbàlà nlá bi èyí; ti àteteḱọ bẹ̀rẹ̀ si isọ lati ọ̀dọ̀ Oluwa, ti a si fi mulẹ fun wa lati ọ̀dọ̀ awọn ẹniti o gbọ́.
**2 Korinti 6:2**
(Nitori o wipe, emi ti gbohùn rẹ li akokò itẹwọgbà, ati li ọjọ́ ìgbàlà ni mo si ti ràn ọ́ lọ́wọ́: kiyesi I, _________ ni àkókò itẹ́wọ́gbà; kiyesi i, nisinsinyi ni ọjọ́ ìgbàlà.)
Àkíyèsí: Àkókò tó dára jù lati gbọ́ ohùn Ọlọrun ni ìgbàtí a ba ngbọ́, ati àkókò to dara jù lati ṣe ìfẹ́ Ọlọrun ni ìgbàtí Ọlọrun ba nfi ìfẹ́ Rẹ hàn wa. Ìdẹ̀kùn ti Satani ṣábà ma nlò jù ni ki o tan awọn ènìyàn ki wọn ma a ronú pé awọn tì ní àkókò tó pọ̀ lati gbé ìgbésẹ̀ yí. Èṣù mọ̀ pé Ẹ̀mí Ọlọrun tó nṣọ fun wa pé a jẹ̀bi yio dákẹ́ nigbàtí a kò ba kà ohùn Rẹ̀ sí. Àìmoye miliọnu ènìyàn ni yio sọnù, ti wọn sì ti npinnu lati tẹ̀lé Jesu ní tòótọ́ lọjọ́ kan lọ́jọ́ iwájú, ṣùgbọ́n "ọjọ́ kan" kò ni dé.

17. Kini ànfàní tó wà ninu gbígba òtítọ́ ati títẹ̀lé òtítọ́?
**Orin Dafidi 119:165**
_________ púpọ̀ li awọn ti o fẹ òfin rẹ ní: kò sì sí ohun ìkọ̀sẹ̀ fun wọn.
**Johannu 8:32**
Ẹ ó sì mọ òtítọ́, òtítọ́ yio si sọ nyin di _________.
**1 Peteru 1:22**
Níwọ̀nbi ẹnyin ti _________ ọkàn nyin mọ́ nípa ìgbọràn nyin si otitọ nípa Ẹmí si ìfẹ́ ará tí kò li ẹ̀tàn, ẹ fẹ ọmọ-nikeji nyin gidigidi lati ọkàn wá.
Àkíyèsí: Alaafia púpọ̀, àábò, ati òmìnira ni yio wọnu ọkàn ati ayé awọn tó ba gbà òtítọ́, ti wọn sì gbọ́ràn si òtítọ́.



18. Kini ìbéèrè ti Jesu bi Peteru ni ìgbà mẹta?
**Johannu 21:17**
O wí fun un nígbà kẹta pé, Simoni, ọmọ Jona, iwọ_________ mi bi? Inú Peteru bàjẹ́, nitorí tí ó wí fun un nígbà ẹkẹta pe, Iwọ fẹràn mi bí? O sì wí fun un pé, Oluwa, ìwọ mọ̀ ohun gbogbo; iwọ mọ̀ pé, mo fẹran rẹ. Jesu wí fun un pé, Maa bọ́ awọn àgùtàn mi.
Àkíyèsí: Ìbéèrè tó ṣe pàtàkì niyi nígbàtí a ba de ìkórita ati jọ̀wọ́ gbogbo ayé wa fun ìfẹ́ Ọlọrun. Njẹ́ o fẹran Rẹ?

# Èsì Rẹ

Òtítọ́ kò le è jẹ́ ohun ti gbogbo ènìyàn yio fẹ́ràn nínú ayé ẹ̀ṣẹ̀ yi, àti pé ọ̀pọ̀ ènìyàn yio ma fẹ́ gba ọ̀nà tó rọrùn julọ nígbà gbogbo. Ṣùgbọ́n Jesu ti fi ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́ Rẹ̀ hàn si ọ nipa fífi ẹ̀mí Rẹ̀ san gbèsè ẹ̀ṣẹ̀ rẹ. Oluwa ní ìpinnu rere fun ayé rẹ. Ìdí niyi ti Ó fi fi òtítọ́ Rẹ̀ hàn ọ́. Njẹ́ o ṣetán láti da ìfẹ́ naa padà nipa fí fun Un ni gbogbo ọkàn rẹ, nipa pé ki o yàn lati gbà Á gẹ́gẹ́ bi Oluwa rẹ, kí o sì má a tẹ̀ le E nibikibi ti Ó ba darí rẹ sí?

ÌDÁHÙN:______________________

Tẹ̀síwájú lati maa dàgbà ati pé ki o sì máa tóbi ninu Ẹ̀mí sí i!
Njẹ́ o ti di alábùkún fún nípaṣẹ awọn Ẹ̀kọ́ Bibeli wọ̀nyí? Awọn ẹ̀kọ́ yi jẹ ọkan ninu awọn Ẹ̀kọ́ Bibeli ti Amaaing Faẹts ní nílẹ̀. Fun àlàyé si lori Prophọ́ eẹy Study Guides tabi fun awọn orukọ awọn ìwé, kaṣẹti tabi àwo ati eré orí-ìtàgé, kàn sí wa ni:

Amazing Facts, Inc.
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678-0909
916-434-3880
www.AmazingFacts.org

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP24.indd 2 12/21/12 12:48 PM